# IBI MOSE -- IGBA EWE RẸ̀ NI ILẸ EGIPTI

**Ẹksodu 2:1-25**

**ẸKỌ 46 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ã! ijinlẹ ọrọ̀ ati ọgbọ́n ati ìmọ Ọlọrun! awamáridi idajọ rẹ̀ ti ri, ọ̀na rẹ̀ si jù awari lọ!" (Romu 11:33).**

**I Inilara Awọn Ọmọ Israẹli ni Ilẹ Egipti**

1 Ẹ̀rù n ba awọn ara Egipti bi agbara awọn Ọmọ Israẹli ti n pọ̀ si i, Ẹksodu 1:8-10; Orin Dafidi 105:23-25

2 Ireti awọn ara Egipti lati yanju wahala yii kùnà lati mú aniyan ọkàn wọn kuro, Ẹksodu 1:11-14

3 Farao fi aṣẹ lile kan lelẹ lati tẹri awọn Ọmọ Israẹli ba, Ẹksodu 1:22; Iṣe Awọn Apọsteli 7:6, 7, 18, 19

**II Ibi ati Isọdọmọ Mose**

1 Jokebedi, iya Mose, pa ọmọ-ọwọ́ rẹ mọ́, o si fi ọmọ rẹ̀ obinrin ṣọ́ ọ, Ẹksodu 2:1-4; Numeri 26:59; Heberu 11:23

2 Ọmọbinrin Farao ri i o si kaanu fun ọmọ ọwọ́ naa, Ẹksodu 2:5, 6

3 Miriamu ṣe ojuṣe ti rẹ̀, o wá ile ẹni iwa-bi-Ọlọrun fun arakunrin rẹ̀, Ẹksodu 2:7-9

4 Ọmọbinrin Farao sọ Mose di ọmọ rẹ̀, Ẹksodu 2:10; Iṣe Awọn Apọsteli 7:20-22

**III Ohun ti Mose Yàn ati Abayọrisi Kikanju Rẹ**

1 Mose yàn lati fi aafin Egipti silẹ lati ni idapọ pẹlu awọn eniyan Ọlọrun, Heberu 11:24-26; Marku 8:35; 10:29, 30; Heberu 11:8-10, 13-16; Johannu 4:32-38

2 Mose wà ninu ibanujẹ fun inilara awọn eniyan rẹ̀, o si gbiyanju ọna idande kan, Ẹksodu 2:11, 12

3 Kikanju ti Mose kanju mu ki awọn Ọmọ Israẹli kọ̀ ọ gẹgẹ bi aṣiwaju tabi oludasilẹ wọn, Ẹksodu 2:13, 14; Iṣe Awọn Apọsteli 7:23-38

**IV Sisalọ Mose si Ilẹ Midiani**

1 Ibinu Farao si Mose mu ki o sá kuro ni ilẹ Egipti, Ẹksodu 2:15

2 Nipa inu rere rẹ̀ si awọn ọmọbinrin Jẹtro, alufaa Midiani kan, a gba Mose si ile baba wọn, Ẹksodu 2:16-22; Gẹnẹsisi 29:10; Iṣe Awọn Apọsteli 7:29

3 Ipọnju awọn Ọmọ Israẹli n pọ̀ si i, wọn si kigbe si Ọlọrun, Ẹksodu 2:23-25; Numeri 20:14-16

## ALAYE

Ọdun pupọ ni o ti kọja laaarin ohun ti o ṣẹlẹ ninu ẹ̀kọ́ wa ikẹyin ninu Majẹmu Laelae, eyi ti o pari pẹlu ikú Jakọbu, ati eyi ti a n sọ nipa rẹ̀ nisisiyii. Nigba naa iba awọn Ọmọ Israẹli ni awọn ọmọkunrin Jakọbu mejila ati awọn ara ile wọn -- iba eniyan diẹ ni wọn jẹ bi a ba fi wọn wé awọn ọgọgọọrun ọna ẹgbẹrun iran wọn ti n gbé ni Egipti lakoko ẹ̀kọ́ wa yii, nigba ti a bi Mose, ẹni ti yoo jẹ aṣaaju wọn.

Igba paapaa ti yi pada. Farao titun ti kò mọ Josẹfu ni o wà lori oyè, nitori naa o rò pe oun kò jẹ ọkunrin ti o gba Egipti kuro ninu agbami iyàn ni gbese kankan rara. O bẹrẹ si i fura si awọn darandaran Goṣeni. Iwe itan sọ fun ni pe awọn ara Egipti ti jiya latẹyinwa labẹ awọn oluṣọ-agutan kan ti wọn jẹ́ ọba. Niwọn bi awọn Ọmọ Israẹli si ti jẹ oluṣọ-agutan, awọn ara Egipti fura si wọn pe iwa wọn ni lati jẹ bakan naa pẹlu awọn ti o ti ṣakoso wọn tẹlẹ ri; ẹru si n bà awọn ara Egipti ohun ti abayọrisi rẹ̀ yoo jẹ bi akoso orilẹ-ède naa ba bọ́ si ọwọ awọn Ọmọ Israẹli.

Ohun kin-in-ni ti Farao ṣe lati daabo bo ilu rẹ̀ ni lati tẹri awọn Ọmọ Israẹli ba ki o si sọ wọn di ẹrú. Ninu ipo yii ni awọn Ọmọ Israẹli ti wọn ti wà ni ominira ri, ti inu wọn si ti n dùn tẹlẹri ti n ṣe laalaa fun ọpọlọpọ ọdun, ti wọn n kọ́ ilu fun awọn oluwa wọn. Ṣugbon eyi ko mu ifẹ awọn ọta wọn ṣẹ lori wọn. Bi a ti n ṣẹ́ wọn ni ìṣẹ́ bẹẹ ni wọn n gbilẹ si i tó ti wọn si n pọ̀ niye.

Nigba pupọ, ipọnju maa n ṣe Onigbagbọ́ ni anfaani pupọ. A le ri i ninu itan ijọ Onigbagbọ́ pe awọn Onigbagbọ́ ti a ṣe inunibini si ni awọn Onigbagbọ́ ti a bukun. Boya ki i ṣe nipa ohun ayé yii, nipa ọrọ̀ ti a n fi oju ara wò, ṣugbọn ọlọrọ̀ ni wọn ninu anfaani ati ibukun ayeraye. Onipsalmu sọ pe o dara ti a pọ́n oun loju; pe ki a to pọ́n oun loju oun ti ṣina. Ninu ipọnju o ti kọ́ ilana Oluwa; ati pe ninu ijolootọ Rẹ̀ si awọn ti Rẹ̀, Ọlọrun ti gba wahala laayè lati wá (Orin Dafidi 119:67, 71, 75).

Dajudaju itan awọn Ọmọ Israẹli ko yatọ. Ipọnju ti wọn ri ni Egipti mu ki wọn ke pe Ọlọrun fun idande. I ba ṣe pe ara ti rọ̀ wọn patapata ki inu wọn si dùn, wọn kì bá tí poungbẹ fun ominira Ilẹ Ileri ti yoo jẹ ti wọn lakoko ti Ọlọrun yàn.

Ipọnju kùna lati mu ki Israẹli dinku niye gẹgẹ bi wọn ti n fẹ, nitori bẹẹ Farao pa aṣẹ miiran, ni èro pe eyi yoo din agbara awọn ẹrú wọnyii kù. Ṣugbọn agbara ti oun kò mọ ri ni oun doju kọ. Awọn obinrin Heberu bẹru Ọlọrun; ofin Ọlọrun ti ko fi àye silẹ fun ni lati pa eniyan ti fẹsẹ mulẹ lọkan wọn (Gẹnẹsisi 9:6). Niwọn bi wọn ti bẹru Ọlọrun ju eniyan lọ, wọn kọ̀ lati pa aṣẹ Farao mọ́.

Bi o ti n du u ni gbogbo ọna, o wa paṣẹ nikẹyin pe gbogbo ọmọkunrin ti a ba bi fun awọn Heberu ni ki a gbé sọ sinu odò nigba ti a ba ri wọn. Farao lero pe ère meji ni oun n mu ṣẹ nipa ofin yii. Ekinni, oun n ké agbara awọn eniyan Heberu ẹ̀yìn-ọ̀la kuru; ekeji, oun n fi awọn eniyan rubọ fun odo, ọ̀kan ninu awọn oriṣa ti awọn ara Egipti n bọ. Dajudaju eyi jẹ nnkan kan ti o fa iparun Egipti nigbooṣe. Nigba gbogbo ni Ọlọrun ni Ọrun ti n dide ni idajọ sori awọn wọnni, awọn ti ko ṣai sin In nikan, ṣugbọn ti wọn tun fi ẹmi awọn eniyan alailagbara rubọ ninu iwa ibọriṣa wọn. Ọpọ orilẹ-ède ni O parun ni apapọ nitori aṣa buburu yii.

Ohun ti i ba dabi ẹnipe o kan dede ri bẹẹ, -- ṣugbọn ti o daju pe ifarahan iṣẹ ọwọ́ Ọlọrun ni – ni otitọ pe pipaṣẹ ti Farao paṣẹ pe ki a pa gbogbo awọn ọmọ-ọwọ ni o yọri si titọ́ ti a tọ́ ẹni ti yoo wá dá Israẹli nide ninu ile ti rẹ̀, ninu inawo ara rẹ̀ ati nipa aṣẹ rẹ̀ pẹlu. Onipsalmu fi oye yé ni nipa iru ọna ipese Ọlọrun bayii, nitori bi o ti n gbe Ọlọrun ga akọwe orin mimọ́ naa wi pe: “Nitõtọ ibinu eniyan yio yìn ọ” (Orin Dafidi 76:10). Ẹkọ wa yii fi otitọ ọ̀rọ alarinrin yii hàn gbangba. Ibinu ati irunu Farao ran awọn ẹni ayanfẹ Ọlọrun naa lọwọ lati ni ironupiwada ti o jinlẹ, o si yọri nikẹyin si didoju ijọba agberaga Egipti bolẹ patapata, ati gbigbe Ọlọrun ga ni gbogbo agbaye (Jọṣua 2:9, 10).

A bí Mose sinu ẹbi Amramu ati Jokebedi, ti i ṣe ẹya Lefi. Iya rẹ̀ gba Ọlọrun gbọ́, bi o si ti ri i pe ọmọ oun jẹ́ arẹwa, o fi i pamọ fun oṣu mẹta. Nigba ti ko si ṣe e ṣe fun un lati fi i pamọ mọ́, o fi i si abẹ iṣọ Ọlọrun ti oun fẹ ti o si bu ọlá fun. Ki o to le ṣe eyi nì, o kọkọ ni lati ni igbagbọ́ -- igbagbọ́ iru eyi ti o fẹrẹ ṣọwọn – si aidẹkun aniyan Ọlọrun lori awọn eniyan ti Rẹ̀. O gbe ọmọ-ọwọ naa sinu apoti kekere kan ti o ti ṣe, o si gbe e saarin koriko ti o hù leti odo. A bu ọlá fun igbagbọ́ rẹ, nitori si ibẹ naa gan an ni Ọlọrun dari ọmọbinrin Farao, ifẹ ẹni ti a rú soke nigba ti o gbọ́ ẹkún ọmọde kekere naa.

Ihumọ ọlọgbọ́n, eyi ti Ọlọrun tikara Rẹ̀ rú soke, pe ki a wá olutọ́ kan ninu awọn obinrin Heberu, mu ki a gbé Mose pada sọwọ iya rẹ̀ fun gbogbo akoko ẹlẹgẹ́ ti a fi tọ ọ dagba. Ko si nnkan kan ti o le ṣe eyi bi ko ṣe ọwọ Ọlọrun. Eyi ni pe a o tọ́ Mose ninu ẹsin Ọlọrun tootọ a o si kọ ọ ni ilana Ọlọrun Ọrun dipo ibọriṣa orilẹ-ède keferi naa. Dajudaju iya rẹ̀ ti sọ fun un nipa awọn majẹmu ati ileri Ọlọrun ti a o mu ṣẹ nigbooṣe, ọkàn ọdọmọkunrin naa si ti tẹ̀ si ẹkọ wọnni nigba ti o tó akoko fun un lati yàn funra rẹ̀.

A kà ninu iwe Heberu pe Mose huwa ọlọgbọ́n nigba ti o ni lati yàn laaarin awọn nnkan ti i ṣe ti Ọlọrun ati nnkan ti ayé. Gẹgẹ bi Abrahamu, oun n ṣafẹri opin kan ti o ga rekọja ohun ti eniyan tabi ayé le fun ni. Ilepa rẹ̀ ni lati tẹ́ Ọlọrun lọrun ati lati sin In bi yoo tilẹ padanu ni ijọba, ọpọ ọrọ̀, ati ọlá, ati irọrun pupọ ti ó wà ninu ayé yii. Wo bi o ti jẹ pe iba eniyan diẹ kiun, nigba naa ati nisisiyii ni o n fẹ fi ara wọn rubọ bi iru eyi!

Ṣugbọn ẹni nla yi, bi o tilẹ jẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun, sibẹ ẹlẹran ara ni; Ọlọrun si ni lati kọ ọ ki o si ṣe e yẹ fun iṣẹ ti yoo wa ṣe. Mose fi hàn pe oun ko i ti ni ẹ̀kọ́ yii ninu ohun ti a kọ silẹ pe o kọ́ ṣe lẹyin ti o jade lọ ba awọn eniyan rẹ̀. Oun ko duro de akoko tabi itọni Ọlọrun ṣugbọn o gbiyanju lati gbẹsan iya ainidi ti ẹrú Heberu kan n jẹ lati ọdọ ọkunrin kan ti o n pọ́n ọn loju. Ninu itara ati aifarabalẹ rẹ̀ Mose pa ara Egipti naa o si bo okú rẹ mọlẹ ninu erupẹ. Ọkàn rere ni Mose fi ṣe eyi. O mọ pe isinru ko tọ́ o si ro pe ninu iru ipo bẹẹ bi eniyan ba lo iwa ipá, kò buru; ṣibẹ ohunkohun ti o wù ki o ṣẹlẹ, a o fi ara wa silẹ fun iya jẹ pupọ bi a ba saré ṣaaju akoko ati eto Ọlọrun.

Jakọbu gba ọna ti ara rẹ̀ lati ri ibukun ti Ọlọrun ti ṣeleri; dipo ki o fi àye silẹ fun Ọlọrun, Jakọbu wa a funra rẹ̀. Abayọrisi rẹ̀ ni pe Jakọbu wá awọn nnkan ti ara dipo awọn ileri majẹmu ati ibukun ẹmi ti Ọlọrun n fẹ ki o ni; niwọn bi o si ti da a ṣe Ọlọrun fi i silẹ lati ṣeto wọn funra rẹ̀. Ọpọlọpọ ọdún ni o fi ṣiṣẹ́ ki o to le ni awọn nnkan ti ara ti Ọlọrun i ba fi fun un pẹlu awọn ibukun ti ẹmi ti Ọlọrun ni ni ipamọ fun un. Aifarabalẹ Mose mu iṣẹ́ aṣekara, ipọnju, iṣẹ́ ati didá wà fun ọdun pupọ ba a, ko si jẹ ki o ni ipá lori awọn Ọmọ Israẹli eniyan rẹ̀ fun igba diẹ.

Bi ọpẹ wa ti pọ to pe a n sin Ọlọrun alaanu, onifẹ ati olubanikẹdun. Ka Orin Dafidi 103:13-18. A ni lati dupẹ pe bi a ba fi aifarabalẹ ṣaaju Ọlọrun, Oun yoo mu wa pada jẹjẹ bi a o ba gbọran, yoo si ba wa wi, yoo si tọ́ wa, yoo si kọ wa lati ma tọ Ọ lẹyin. Ka Isaiah 40:11; Orin Dafidi 23:1-6; Johannu 10:1-18.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni orukọ baba, iya, arabinrin ati arakunrin Mose?
2 Ki ni ṣe ti a gbe Mose sinu apoti ti a fi eweko ṣe nigba ti o wà ni ọmọ-ọwọ́?
3 Ki ni ipa ti arabinrin Mose kó lati fi i pamọ?
4 Ọna wo ni arabinrin Mose gba fi lo ọgbọ́n ti o dara ti o si ṣọwọn? Iwọ ha ro pe ti rẹ̀ ni ọgbọ́n naa, tabi Ọlọrun ni o tọ́ ọ?
5 Ta ni sọ Mose di ọmọ, anfaani wo ni o si ni nipa isọdọmọ bẹẹ?
6 Iru iha wo ni Mose kọ si ile ọba ti i ṣe ti rẹ̀ ati anfaani rẹ̀ nigba ti o dagba tan?
7 Itara ọ̀di wo ni Mose ṣe?
8 Iha wo ni ọba ati awọn eniyaa rẹ kọ si iwa Mose yii?
9 Nibo ni Mose lọ?
10 Lẹyin iwa aifarabalẹ Mose ati lilọ rẹ kuro ni Egipti, iru iha wo ni awọn Ọmọ Israẹli kọ si Ọlọrun?